# OKUN PUPA; IṢẸGUN ISRAẸLI LORI EGIPTI

**Ẹksodu 13:17-22; 14:1-31; 15:1-21**

**ẸKỌ 57 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Nipa igbagbọ́ ni nwọn là okun pupa kọja bi ẹnipe ni iyangbẹ ilẹ" (Heberu 11:29).**

**Ibẹrẹ Ijadelọ**

Awọn Ọmọ Israẹli bẹrẹ irin-ajo iṣẹgun wọn lọ si Ilẹ Kenaani. Ki i ṣe ọna ti o jìn pupọ, nitori a ranti pe awọn ọmọ Jakọbu ti lọ lati Kenaani si Egipti lẹẹmeji lati ra ọkà; nigba ti Jakọbu si kú, Josẹfu ati ogunlọgọ awọn ara ile ati iranṣẹ rẹ̀ ni o pada si Kenaani lati sinku baba rẹ̀. I ba ṣe pe awọn Ọmọ Israẹli ti tẹle aṣẹ Mose ki wọn si ti gbẹkẹle Ọlọrun patapata, lai ṣe aniani wọn i ba ti de ilẹ-ini wọn lai pẹ lọ titi. Ṣugbọn nitori aigbagbọ́ ati aigbọran, wọn rin kaakiri fun ogoji ọdun, titi gbogbo awọn ti o ju ogún ọdún lọ nigba ti wọn fi Egipti silẹ fi kú, ayafi Kalebu ati Jọṣua.

Ọlọrun ti ṣe iṣẹ-iyanu nla pupọ lati mu ki awọn ara Egipti jẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ lọ, ṣugbọn iṣẹgun ti o tobi ju bẹẹ wà niwaju. Ko pẹ lẹyin ti ara awọn ará Egipti balẹ lẹyin idaamu ikú akọbi wọn ni wọn wa ro pe ko tọ ti wọn fi dá awọn ẹru wọn silẹ. Ṣe awọn Ju ti ṣe iṣẹ ribiribi fun awọn onroro oluwa wọn, lilọ wọn yoo si dá wọn lagara pupọ.

Nigba ti Farao ri ọna ti wọn ti dojukọ (ko ṣe e ṣe fun aadọjọ ọkẹ eniyan (3,000,000) pẹlu gbogbo ọ̀wọ́-ẹran ati gbogbo-ẹran wọn lati ro pe awọn le fi oju-ọna ti wọn rin pamọ), o paṣẹ ki awọn ọmọ-ogun rẹ lepa pẹlu ẹṣin ati kẹkẹ. Ọna kan ti o ṣe taara ju bẹẹ wà ti o ṣe e ṣe ki ọba naa ro pe wọn yoo gbà; ṣugbọn nitori o la ilẹ awọn Filistini ti ko ni ṣe alaiba wọn jagun kọja, Ọlọrun mu ki awọn Ọmọ Israẹli gba ọna Okun Pupa. Ọlọrun mọ pe awọn eniyan Oun ko i ti ni agbara to lati jagun ni gẹrẹ ti a tu wọn silẹ loko ẹru, nigba ti o jẹ pe wọn ko ti i ni anfaani lati jà fun ẹtọ wọn tabi lati gbeja ara wọn. Boya Farao ti ro pe wọn o ṣegbe nigba ti wọn dori kọ ọna hiha ti o wà laaarin awọn oke giga, ti Okun Pupa si wà niwaju wọn. Boya o fi wọn rẹrin ẹlẹya, o si rò pe yoo rọrun lati lepa wọn ati lati mu wọn pada si Egipti.

**Itọni Ọlọrun**

Ṣugbọn Ọlọrun n tọ́ awọn eniyan Rẹ̀. Ni ọsan ọwọ̀n awọsanma a ṣiwaju lati ṣamọna wọn ati lati jẹ́ ibori kuro ninu oorun gbigbona naa (Orin Dafidi 105:39). Ni oru ọwọ̀n iná ni o maa n ṣaaju wọn bi wọn ba ti n rin lọ, o si jẹ imọlẹ fun wọn. Lati inu ọwọ̀n naa ni Ọlọrun tikara Rẹ̀ ti maa n ba wọn sọrọ, lati fi hàn wọn pe Oun wà nibẹ pẹlu wọn (Ẹksodu 16:10, 11; 33:9). O mu wọn de ipo hiha yii ki O ba le tun fi agbara nla Rẹ̀ hàn wọ́n.

Nigba ti a ba de ibi hiha a ko gbọdọ kùn pe Ọlọrun ko ṣe itọju wa tó. A ni lati gbagbọ́ pe Oun mọ ohun ti o dara ju lọ, ki a si tẹriba labẹ ifẹ Rẹ̀ ki O ba le gba ògo ni igbesi-ayé wa.

O yẹ ki awọn Ọmọ Israẹli ti kọ́ bi a ti i gbẹkẹle Ọlọrun lakoko yii, lẹyin gbogbo iṣẹ-iyanu ti o ti ṣe loju wọn ni Egipti; ṣugbọn lẹsẹkẹsẹ ti wọn ri awọn ara Egipti ti n lepa wọn ẹru bà wọn. Wọn ṣe bi awọn yoo kú, wọn si woye pe isinru ni Egipti san ju ikú lọ.

**Ogun Oluwa**

Mose kò ba wọn wi fun ṣiṣe ojo, nitori o mọ pe igbagbọ́ wọn kere. O fi ọrọ daradara wọnyii ki wọn laya: "Ẹ má bẹ̀ru, ẹ duro jẹ, ki ẹ si ri igbala OLUWA, . . . . OLUWA yio jà fun nyin, ki ẹnyin ki o si pa ẹnu nyin mọ́." Ko ha ni jẹ ohun iyanu lati duro jẹ ẹ ki wọn wo Ọlọrun bi O ti n jà fun wọn? A ni anfaani yii kan naa lonii. Ọlọrun n fẹ ki a duro jẹ ẹ, ki a si jẹ ki Oun yanju gbogbo adiitu wa fun wa. A kò gbọdọ ṣe aniyan tabi ki a gbọ̀n jinnijinni nigba ti ọjọ ibi ba de; ṣugbọn bi a ba kó aniyan wa tọ Jesu lọ Oun yoo mu ohun gbogbo wá si titọ.

**Yí Wọn Ká**

Gbiyanju lati ronu iru ipo ti ogunlọgọ awọn eniyan yii wà. Oke nla wà lọtun ati losi wọn awọn ọmọ-ogun Egipti wa lẹyin wọn, alagbalugbu omi okun si wa niwaju wọn. Ranti pe ẹsẹ̀ ni wọn fi n rin lai si ihamọra ogun lati fi jà. Ko si ohun ti wọn i ba fi kan ọkọ rekọja. Ṣugbọn wọ́n ní Ọlọrun! Ọlọrun ni apata ati ohun-elo ijà wọn. Gbogbo ohun ti wọn ni i ṣe ni pe ki wọn duro jẹ ẹ ki wọn si ri agbara Rẹ̀.

Ọwọ̀n awọsanma ti dari awọn eniyan naa de ihin, ṣugbọn o pada o si duro lẹyin agọ Israẹli ti awọn ara Egipti kò fi le ri wọn. Ṣugbọn fun awọn Ọmọ Israẹli imọlẹ ni o jẹ́. Bẹẹ gẹgẹ ni Ọrọ Ọlọrun ri lonii fun Onigbagbọ́; o jẹ imọlẹ ati amọna si Ọrun; ṣugbọn fun ẹlẹṣẹ ti o kọ̀ lati fiyesi i o jẹ idajọ kikan ati okunkun. Ni gbogbo oru naa awọsanma naa ṣokunkun to bẹẹ laaarin awọn ara Egipti ati awọn Ọmọ Israẹli ti wọn kò fi le ri ara wọn.

A há awọn Ọmọ Israẹli mọ́ ni gbogbo ọna, sibẹ Ọlọrun ni ki wọn tẹsiwaju. Njẹ iwa werè ni eyi? Boya nigba miiran a maa n ro pe aṣẹ Ọlọrun kò fa ọgbọ́n yọ, ṣugbọn nigba gbogbo ni Oun maa n lana silẹ fun ni lati le ṣe ohun ti O n beere lọwọ wa. Ọlọrun ni ki Mose na ọpa rẹ̀ jade sori Okun Pupa, awọn omi yoo si pinya ki awọn eniyan naa le rin kọja lori ilẹ gbigbẹ. Njẹ ko ha ni ya ọ lẹnu lati de ibi odo nla kan ki omi ibẹ si pinya lojiji ki wọn si duro bi okiti niha mejeeji ki ọna si wà laaarin? Ṣugbọn bi Ọlọrun ti jẹ Alagbara to ni yii! Ọna yii ni lati jẹ eyi ti o gbooro nitori gbogbo awọn eniyan wọnni ati awọn ẹran wọn ni o ni lati kọja ni alẹ ọjọ kan naa.

**Kẹ̀kẹ́ Ti Ó Rún Wómuwómu**

Nigba ti Ọlọrun ri i ti awọn ará Egipti n tẹle awọn Ọmọ Israẹli wọ inu okun pupa, O mú ki ẹsẹ̀ kẹkẹ wọn yẹ̀ kuro ti wọn kò fi le bá wọn. Wo idarudapọ ti ó ṣẹlẹ lori iyanrin isalẹ okun: lara awọn kẹkẹ kò le rìn mọ́ nitori ẹsẹ̀ wọn ti yọ kuro; awọn kẹkẹ miiran kò rí àyè kọja lara awọn ti ó wà ninu idaamu; olukuluku si n kigbe si ẹni keji fun iranwọ.

Loju kan naa ti awọn Ọmọ Israẹli kọja tán, omi rọ́ pada bọ̀ sori awọn onikupani wọn, ó si bo gbogbo wọn mọ́lẹ̀ kò si si ẹni ti ó là. Nigba ti ilẹ mọ́, awọn eniyan Ọlọrun rí òkú awọn ará Egipti ti omi ti gbá sẹba okun. "Bayi li OLUWA gba Israẹli là li ọjọ́ na lọwọ awọn ara Egipti."

**Orin Mose**

Bawo ni ayọ awọn ọmọ Ọlọrun ti pọ̀ to! A ti gbà wọn kuro ni oko-ẹru Egipti, a si ti pa awọn amunisin wọn run. Mose kọ orin iyin aladun kan fun awọn eniyan naa, eyi ti o jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ọrọ akewi ti o larinrin ju lọ laye. O jẹ orin idande wọn nipa aanu Ọlọrun. A ni akọsilẹ ninu Iwe Ifihan nipa awọn miiran ti wọn kọ orin yii, eyi ti a n pe ni Orin Mose, wọn si sọ siwaju pe: "Titobi ati iyanu ni awọn iṣẹ rẹ, Oluwa Ọlọrun Olodumare; ododo ati otitọ li ọ̀na rẹ, iwọ Ọba awọn orilẹ-ede. Tani ki yio bẹ̀ru, Oluwa, ti ki yio si fi ogo fun orukọ rẹ? nitori iwọ nikanṣoṣo ni mimọ́: gbogbo awọn orilẹ-ède ni yio si wá, ti yio si foribalẹ niwaju rẹ; nitori a ti fi idajọ rẹ hàn" (Ifihan 15:3, 4).

A ti sọ agbara ẹni buburu ni dasan; a si fi idajọ Ọlọrun hàn fun gbogbo eniyan. Gẹgẹ bi a ti mu Israẹli jade kuro ninu oko-ẹru Egipti, bẹẹ gẹẹ ni a ti n gba wa kuro ninu igbekun eṣu nigba ti a ba ri igbala; bẹẹ ni a o si ṣe gba wa kuro ninu ayé ẹ̀ṣẹ yii lọ sinu Ọrun nigba ti Jesu ba de. Lila Okun Pupa kọja jẹ apẹẹrẹ iribọmi wa (1 Kọrinti 10:1, 2).

## AWỌN IBEERE

1. Njẹ Farao jẹ ki awọn eniyan naa lọ ni alaafia lẹyin ti wọn jade?
2. Awọn taa ni o rán lati lepa wọn?
3. Ki ni awọn Ọmọ Israẹli ṣe nigba ti wọn ri awọn ti n lepa wọn? Njẹ eyi ni ó tọ́ ki wọ́n ṣe?
4. Bawo ni a ṣe n dari awọn Ọmọ Israẹli lọsan? Ati ni òru?
5. Ki ni ṣẹlẹ si awọsanma nigba ti awọn ara Egipti sún mọ́ wọn?
6. Ki ni Ọlọrun sọ fun awọn Ọmọ Israẹli lati ṣe?
7. Ki ni ṣẹlẹ nigba ti Mose na ọpa rẹ̀ jade?
8. Bawo ni awọn Ọmọ Israẹli ṣe la Okun Pupa já?
9. Njẹ awọn ara Egipti kọja? Ki ni ṣe idena?
10. Ki ni orin ti Mose kọ?